# ORÍ ÒKÈ INÁ ÀTI IṢẸ́ ÌYANU

Olú Ilé Iṣẹ́ Ìránṣẹ́, Ìpínlẹ̀ Èkó, Nigeria.

## OSÙ KEJE, ỌDÚN 2021

**Agbára Gbọ́dọ̀ Pàrọ̀ Ọwọ́**

**(Iṣìn Omi Iná)**

## OṢÙ KEJE 2021 – ÀDURA OGUN (APÁ KINÍ)

7:00 am – 7:15 am Àdúrà ìbẹ̀rẹ̀

7:15 am – 7:45am Orin Ìyìn àti Ijọ́sìn

7:45 am – 7:50 am Orin  Ìbẹ̀rẹ̀

7:50 am – 8:05 am Ijẹ́rì

8:05 am – 8:15 am Wákàtí Ìṣìpẹ̀ Àdáṣe

8:15 am - 8:30 am Orin àwọn Akọrin

8:30 am – 10:30 am Ìwáásù àti Iṣẹ́ Ìránṣẹ́

10:30 am – 11:00 am Ọrẹ àti Ìparí ìpàdé

**TANI NṢE T'OLUWA?**

1. Tani nṣe t'Oluwa, ti yoo sin Jesu?
   Tani y'o ran lọwọ, lati gb'ẹmi la?
   Tani y'o kọ aye, k'o dojuk'ọta?,
   Tani nṣe t'Oluwa, ti y'o jiṣẹ fun?
   Nipa ipe anu, nipa or'ọfẹ
   T'Oluwa l'awa nṣe, ti Olugbala.

2. Ki ṣe fun fadaka tabi ere kan
   Li a ṣe f'ara wa rubọ f'Oluwa
   Ifẹ l'o wa wa ri, eyi l'o nrọ wa
   Ẹniti Jesu pe ko le ṣai jade
   Nipa ifẹ Rẹ nla, at'or'ọfẹ Rẹ
   T'Oluwa l'awa nṣe, ti Olugbala

3. Jesu ki ṣe wura, li O fi ra wa:
   O f'Ẹmi Rẹ ra wa, lati fi ṣ'ọṣọ
   'Wọ f'ibukun Rẹ kun, ẹni tọ ọ wa
   'Wọ fun wa ni ifẹ, ati ominira
   Nipa irapada, nipa or'ọfẹ
   T'Oluwa l'awa nṣe, ti Olugbala

4. Ija na le kikan, ọta le tẹgun
   Ko s’ẹni le bori, ogun Ọba wa,
   Labẹ asia Rẹ, iṣẹgun daju
   Nitori otọ Rẹ, y’o bori dandan
   Pẹl’ayọ lao jọsin, nipa or’ọfẹ
   T’Oluwa l’awa nṣe, ti Olugbala

## **ỌRỌ AGBÁRA**

1. Nípa agbára tó wà nínú ẹ̀jẹ̀ Jésù, mo sọ̀rọ̀ sórí ayé mi lónìí wípé, nkò ní jẹ́ ẹrú pẹpẹ yòówù, ní orúkọ Jésù.
2. Olúwa, nínú ètò tònìí, rán agbára Rẹ láti yọ mí kúrò nínú gbogbo pàkúté tí ọ̀tà dẹ láti fi dè mí mọ́lẹ̀, ní orúkọ Jésù.
3. Gbogbo ẹ̀bùn ìkà tó dogun nínú ayé mi, òní ni àwọn iṣẹ́ láábi rẹ dópin nínú ayé mi, gba iná, ní orúkọ Jésù.
4. Ẹ̀bùn ibi yòówù, tí ọ̀tá lò láti fi já ògo mi gbà, òní lòpin rẹ, gba iná, ní orúkọ Jésù.
5. Ẹ̀yin adánilóró mi, iṣẹ́-ìránṣẹ́ yín lórí ayé mi yóò dópin lónìí, ẹ dá ara yín lóró, kí ẹ sì kú, ní orúkọ Jésù.
6. Àwọn ogun tó njẹyọ lọ́wọ́lọ́wọ́ nínú ayé mi, àkokò rẹ dópin lónìí, gba ìfopinsí, ní orúkọ Jésù.
7. Ọlọ́run, dìde, jẹ́ kí agbára láti tayọ bàle àyànmọ́ mi báyìí, ní orúkọ Jésù.

## **ÀDÚRÀ ÀDÁGBÀ**

**Ìjẹ́wọ́: Orin Dáfídì 91**

1. Ọlọ́run, dìde, kí O sì fàtu ohunkóhun tí O kò gbìn, sínú Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
2. Ọlọ́run, jẹ́ kí iná ìsọjí, bà lé Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.

3. Ọlọ́run, dìde, ki O si tumi silẹ kuro ninu gbogbo ogun ti nko mọ ibiti wọn ti njẹyọ bọ, ní orúkọ Jésù.
4. Ìmọ̀ràn ìkà ìkọ̀kọ̀ lòdì sími, di wèrè, ní orúkọ Jésù.
5. Ọlọ́run, dìde, fa idà àwọn ọ̀tá mi yọ, jẹ́ kí ó bà lé wọn lórí, ní orúkọ Jésù.
6. Gbogbo ìránṣẹ́ àjẹ́ tí wọ́n yàn lòdì sími, kí àṣírí rẹ tú, ko sì gba ìtìjú, ní orúkọ Jésù.
7. Ọlọ́run, dìde, fọ́ orí àwọn drágónì omi tó lòdì sími, ní orúkọ Jésù.

## ÀDÓ Ọ̀RỌ̀ NÁÀ

**Deuteronomi 20:4** Nítorípé OLÚWA Ọlọ́run nyín ni mbá nyín lọ, láti bá àwọn ọ̀tá nyín jà fún nyín, láti gbà nyín là.

**Rómù 8:31** Njẹ́ kíli àwa ó hà wi sí nkan wọ̀nyìí? Bí Ọlọ́run bá wà fún wa, tani yóò kọ ojú ìjà sí wa?

**Rómù 8:39** Tàbí òkè, tàbi ọ̀gbun, tàbí ẹ̀dá míràn kan ni yóò le yà wá kúrò nínú ìfẹ́ Ọlọ́run, tí ó wà nínú krístì Jésù Olúwa wa.

**Isaiah 41:13** Nítorí èmi Olúwa Ọlọ́run rẹ yóò di ọwọ́ ọ̀tún rẹ mú, èmi ó wì fún ọ pé, Má bẹ̀rù; èmi ó ràn ọ̀ lọ́wọ́.

**Efesu 6:10** Lákotán, ará mi, ẹ jẹ́ alágbára nínú Olúwa, àti nínú agbára ipá rẹ.

**Orin Dáfídì 108:13** Nípasẹ̀ Ọlọ́run li àwa ó ṣe akin; nítorí òn ni yóò tẹ àwọn ọ̀tá wa mọ́lẹ̀.

**1 Johannu 5:4** Nítorí olukúlúkù ẹnití a bí nípa ti Ọlọ́run ó ṣẹ́gun ayé: èyí sì ni ìṣẹ́gun tí ó ṣẹ́gun ayé, àní ìgbàgbọ́ wa.

**II Kọ́ríntì 10:4** (Nítorí ohun ìjà wa kì íṣe ti ara, ṣùgbọn ó lí agbára nínú Ọlọ́run láti wó ibi gíga palẹ̀;)

**Kólóssè 2:15** Ó sì ti já àwọn ìjọba àti agbára kúrò lí ara rẹ, ó sì ti dójútì wọn ní gbangba, ó nyọ ayọ̀ ìṣẹ́gun lórí wọn nínú rẹ.

**Lúkù 10:19** Kíyèsì i, èmi fún nyín lí àṣẹ́ láti tẹ ejò àti akèkè mọ́lẹ̀, àti lórí gbogbo agbára ọ̀ta: kò sì sí ohun kan bí ó ti wù kí ó ṣe, tí yóò pa nyín lára.

**Òwe 24:16** Nítorípé olóotọ́ a ṣubú nígbà méje, a sì tún dìde: ṣùgbọ́n ènìyàn búburú yóò ṣubú sínú ibi.

**II Kọ́ríntì 2:14** Ṣùgbọ́n ọpẹ́ ni fún Ọlọ́run, ẹnití nyọ̀ ayọ̀ ìṣẹ́gun lórí wa nígbàgbogbo nínú Krístì, tí ó sì nfi orùn ìmọ̀ rẹ̀ hàn nípa wa níbi gbogbo.

**II Kọ́rínti 15:55** Ikú, oró rẹ dà? Isà òkú, iṣẹ́gun rẹ dá?

**Jóṣùa 10:8** OLÚWA  sì wí fún Jóṣùa pé, Má ṣe bẹ̀rù wọn: nítorítí mo ti fí wọn lé ọ lọ́wọ́; kì yóò si ọkùnrin kan nínú wọn tí yóò le dúró níwáju rẹ.

**Ifihan 12:11** Nwọ́n sì ṣẹ́gun rẹ nítorí ẹ̀jẹ̀ Ọ̀dọ-Àgùntàn na, àti nítòrì ọ̀rọ̀ ẹ̀rí wọn, nwọn kò sí fẹ́ran ẹ̀mi wọn àní tìtì dé ìkú.ọ

**<u>ADÚRÀ SÓRÍ OMI</u>**

1. Babá mi, mo dúpẹ́ lọ́wọ́ Rẹ fún dídá omi gẹ́gẹ́ bí ọ̀kan lára adìtú àrà ìṣẹ̀dá Rẹ. Olúwa, Ẹ ṣeun nítorí omi jẹ́ àpẹrẹ Ẹ̀mí Mímọ́. Omi nfọ̀ nkan, sọjí, tẹ́lọ́rùn, tùlára, mú dúró, wẹ̀ mọ́, ó sì nmú nkan dàgbà.
2. Olúwa, dìde nípa agbára àjínde Rẹ, kí O sì mí sínú omi yìí. Jẹ́ kí iná Ẹ̀mí Mímọ́ ṣíji bo omi yìí, ko sì sọ ọ di ìwòsàn atòkèwá, omi ìṣẹ̀dá, omi tó nrún ẹ̀mí òkùnkùn jégé-jégé, ajíra atòkèwà àti apa kòkòrò atòkèwá, ní orúkọ Jésù.

3. Jẹ́ kí ohun gbogbo tó nbẹ nínú omi yìí gbé iná tí kò ṣé pa, ti yóò dójú ti gbogbo irúgbìn òkùnkun nínú ẹ̀jẹ̀ àti ní gbogbo àgọ́ ara mi, sì jẹ́ kí o pe gbogbo májèlé tó faraṣin lágọ̀ ara mi níjà,  ko sì tì í jáde, ní orúkọ Jésù.

4. Baba Olúwa, bí nó se mú omi yìí, jẹ́ kí agbára omi ìyè dàpọ̀ mọ́ ọ, kí ó si sọ̀ ìgbà èwe mi dọ̀tun bí tí idì, jẹ́ kí ẹ̀mí ọgbọ́n, ẹ̀mí òye, ẹ̀mí ìmọ̀ràn àti ipá, ẹ̀mi ìmọ̀ àti ẹ̀mi ìbẹ̀rù Olúwa ṣinmi lé ayé mi, ní orúkọ Jésù.

5.  Olúwa, bí nó se mu omi yìí, jẹ́ kí ó fọ̀ gbogbo irúgbìn òkùnkùn nínú ayé mi dànù, kí ó sì pa gbogbo ibànùjẹ́ àti omi ìkorò tó nyọ ayé mi lẹ́nu rẹ́, ní orúkọ Jésù.

6. Agbárákágbara to ntakò  ìpinnu àti ètò Ọlọ́run fún ayé mi, máa ṣí dànù nípa omi iná yìí, ní orúkọ Jésù.

7. Ọlọ́run dìde, jẹ́ kí omi yìí tú gbogbo ìwo òkùnkùn tí wọ́n gbìn lòdì sí ayé mi ká, kí ó sì parun gbogbo pẹpẹ tí wọ́n mọ lòdì sí àyànmọ́ mi lágbégbè mi, ní orúkọ Jésù.

8. Ìwọ omi yìí, fọ àìsàn, amódí, àìléra àti àrùn títí dójú ikú jáde kúrò nínú ayé mi, ní orúkọ Jésù.

9. Gbogbo ẹ̀yà ara mi tó ti dòkú, gba ìyè bí óò ṣe ma ṣalábàpádè omi iná yìí, ní orúkọ Jésù.

10. Bàbá, jẹ́ kí omi iná yíi tú ìwà ìkà olóríkúnkun àti àjẹ olóríkúnkun lágbégbè mi ka, ní orúkọ Jésù.